# ÀJỌ ỌSẸ

## Ẹksodu 23:14-17; Lefitiku 23:15-22; Deuteronomi 16:9-12; Iṣe Awọn Apọsteli 2:1-18, 37-41

## ẸKỌ 87 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ mu gbogbo idamẹwa wá si ile iṣura" (Malaki 3:10).**

**Awọn Ajọ**

Oluwa wi fun awọn Ọmọ Israẹli pe wọn ni lati pa ajọ mẹta mọ́ laaarin ọdun, ni akoko ti gbogbo awọn ọkunrin ni lati farahan niwaju Oluwa. Wiwá awọn obinrin ki i ṣe dandan, ṣugbọn o daju pe ọpọlọpọ ninu wọn ni yoo maa ba awọn ọkunrin pa ajọ yii mọ́. Lai si aniani, wọn o maa wo ọna fun igba ti wọn o le pejọ pọ̀ pẹlu awọn eniyan Ọlọrun ni idapọ ati isin ni akoko ajọ wọnyii lati ri ibukun Rẹ̀ gbà.

A n pe ekinni ni Ajọ Irekọja, eyi ti wọn n ṣe ni iranti idasilẹ wọn kuro ni Egipti. Ekeji, Ajọ Ọsẹ jẹ́ ifi imoore hàn fun Olufunni ni ikore. Awọn eniyan gbagbọ́ pe o tun jẹ iranti fifi Ofin fun ni, ounjẹ ti Ẹmi ti a n fi bọ́ ọkàn. "Enia kò ti ipa onjẹ nikan wà lãye, bikoṣe nipa gbogbo ọ̀rọ ti o ti ẹnu OLUWA jade li enia wà lãye" (Deuteronomi 8:3). Ajọ Agọ, tabi Ajọ ikorewọle ni ẹkẹta.

**Pentekọsti**

Niwọn igba ti o jẹ pe a ti kọ́ ẹkọ nipa Ajọ Irekọja ti a o si tun kọ́ ẹkọ nipa Ajọ Agọ, a o kọ́ ẹkọ nihin nipa ajọ keji, eyi ni ni Ajọ Ọsẹ tabi Ọsẹ awọn ọsẹ, nitori wọn ni lati ka ọsẹ meje lati ibẹrẹ ikore lati le mọ iye ọjọ ajọ naa. Nigba miiran a maa n pe e ni Ajọ ikore. O si tun ni orukọ miiran sibẹ: Ajọ Pẹntekọsti, nitori o jẹ́ aadọta ọjọ lẹyin Irekọja. Pẹntekọsti jẹ ọ̀rọ̀ ti a mu lati inu ede Griki (Greek) itumọ eyi ti i ṣe aadọta.

A ti kẹkọọ pe ni ọjọ keji Isinmi ti Irekọja, awọn Ọmọ Israẹli yoo mu ẹbọ ọkà wá -- ẹbọ idi ọkà, -- nitori ibẹrẹ ikore ni. A n pe eyi ni ẹbọ akọso a gbọdọ fi akọso ṣe irubọ fun Oluwa, dajudaju ọkà barli ni eyi nitori ọkà barli maa n tete gbó ṣaaju alikama. Ninu Lefitiku 23:14, a kà pe awọn eniyan naa kò gbọdọ jẹ ninu ikore naa – i baa ṣe ọkà tútù ninu ìpẹ́, ọkà gbigbẹ, tabi akara - titi a o fi ṣe irubọ yii si Oluwa. Ki i ṣe kiki pe ẹbọ fifi idi-ọkà yii n sọ ikore di mimọ́ nikan ṣugbọn ó mú ki o daju. "Njẹ bi akọso ba mọ́, bẹ̃li akopọ" (Romu 11:16).

Ọsẹ meje lẹyin ti wọn ba ti ṣe ẹbọ fifi idi-ọka ti akọso, awọn Ọmọ Israẹli ni lati mu iṣù akara meji ti ọkà alikama gẹgẹ bi akọso, pẹlu ẹbọ sisun wọn wá, lati fi ara wọn rubọ. Nigba Ajọ irekọja, kiki akara alaiwu ni wọn gbọdọ jẹ eyi ti i ṣe apẹẹrẹ mimú ẹ̀ṣẹ kuro ni ayé wọn ati lati ṣe iranti akara ti wọn fi ikanju ṣe nigba ti wọn n jade kuro ni Egipti; ṣugbọn ni akoko ajọ yii wọn o jẹ akara wiwu ni imoore fun ounjẹ oojọ wọn, eyi ti a n fi iwukara si, tabi ohun ti n mu akara di wiwu. Eyi ni a n pè ni ajọ ọsẹ.

**Ọrẹ Atinuwa**

Ki i ṣe kiki pe wọn gbọdọ mu ọrẹ wá nikan gẹgẹ bi Ọlọrun ti paṣẹ, ṣugbọn O tun fi àye silẹ fun olukuluku lati mu ọrẹ atinuwa wá gẹgẹ bi o ba ti n fẹ lati inu ọkan rẹ wa. Wọn o mu ọrẹ atinuwa wá gẹgẹ bi Ọlọrun ba ti bukun wọn. Gẹgẹ bi eniyan ti maa n layọ lonii nigba ti o ba fi fun Oluwa lati inu ọkàn rẹ̀ wá, i baa ṣe akoko rẹ̀, tabi talẹnti, tabi ohun ini, bakan naa ni eyi jẹ́ akoko ayọ̀ nla – ninu yinyin ati didupẹ lọwọ Ọlọrun fun ikore ti O fi fun wọn. Wọn tun n yọ̀ ninu idasilẹ wọn bi wọn ti n boju wo ẹyin wo akoko naa ti wọn jẹ́ ẹrú awọn ara Egipti. Lọna kan naa a maa n yin Ọlọrun logo nigba ti a ba ronu igbesi-ayé ti a n gbé tẹlẹ ri, ati gẹgẹ bi Ọlọrun ti dá wa silẹ kuro ninu ipo ẹrú Satani. A n yọ̀ ninu idasilẹ ti a ni nisisiyii.

A tun fun wọn ni ofin kan pẹlu (eyi ti a kọ silẹ ninu Lefitiku 19:9), lati fi awọn igun oko wọn ati awọn idi ti a gbagbe silẹ (Deuteronomi 24:19) fun awọn talaka, awọn opó, ati awọn alejo. A ranti pe nipasẹ ofin yii ni Oluwa ṣe itọju Rutu. Oun jẹ́ obinrin ara Moabu, alejo ni ilẹ Israẹli, aya ọmọkunrin Naomi. O yàn lati sin Ọlọrun jù lati wà pẹlu awọn eniyan rẹ̀. Oluwa si pese fun un nipa ipèṣẹ́ ti o ṣà ninu oko Boasi. Awọn eniyan Ọlọrun maa n ro ti awọn ti o wà ninu aini bẹẹ nipa ti ara ni akoko yii, ati pataki ju lọ awọn alaini nipa ti ẹmi. O ṣe ohun pataki lati gbọran si aṣẹ Ọlọrun ninu ohun keekeekee paapaa, ki ẹbọ wọn ma ba jẹ eyi ti a kò tẹwọgba. Sibẹ Ọlọrun beere igbọran, a si kà ninu 1 Samuẹli 15:22 "Igbọran sàn jù ẹbọ lọ."

**Ọjọ Pẹntekọsti**

Eyi ti o jẹ́ iyanu ju lọ ninu gbogbo Ajọ Pẹntekọsti ti a ti i ṣe ri ni eyi ti a n pe ni Ọjọ Pẹntekọsti, eyi ti a kọ silẹ nipa rẹ ninu Iṣe Awọn Apọsteli ori keji. O jẹ́ aadọta ọjọ gan an, ni wakati kan naa gẹgẹ ("wakati kẹta ọjọ"), lẹyin ti a kan Jesu mọ́ agbelebu.

A pa Jesu, Ọdọ-Agutan Irekọja wa ni akoko pipa Ọdọ-agutan Irekọja. A sin In, O si jinde ni ijọ kẹta. O si di "akọbi ninu awọn ti o sùn" (1 Kọrinti 15:20).

Ni gẹrẹ ki Jesu to goke lọ si Ọrun, O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe a o fi Ẹmi Mimọ́ wọ̀ wọn lai pẹ́ (Iṣe Awọn Apọsteli 1:5). Wọn kò mọ ọjọ ti yoo jẹ gan an, ṣugbọn wọn duro ni yara oke ni Jerusalẹmu gẹgẹ bi Jesu ti sọ fun wọn pe ki wọn ṣe. Iṣe Awọn Apọsteli ori kin-in-ni, ẹsẹ̀ kẹrinla (1:14) sọ fun wa pe "awọn wọnyi fi ọkàn kan duro si adura ati si ẹ̀bẹ." Wọn ni itara lati tan Ihinrere kalẹ, ṣugbọn Jesu ti paṣẹ fun wọn pe ki wọn "duro dè ileri Baba" (Iṣe Awọn Apọsteli 1:4).

Bi ọjọ ajọ naa ti n sun mọle, lai si aniani wọn kun fun iyin ki i ṣe kiki fun ohun ti Ọlọrun ti ṣe fun wọn nikan ṣugbọn fun ẹbun Ẹmi Mimọ́ ti a ti ṣeleri fun wọn. Wọn wà ni yara oke ni ọkàn kan, lojiji iró kan si ti Ọrun wá bi

iro iji nla ti o kun gbogbo ile naa. Gbogbo wọn si kun fun Ẹmi Mimọ́, wọn si bẹrẹ si i fi ède titun sọrọ, gẹgẹ bi Ẹmi Mimọ́ ti fun wọn ni ohùn.

Ninu awọn ero ti o pejọ ninu ilu fun ajọ naa ni a ri awọn eniyan lati ọpọlọpọ orilẹ-ède. Awọn wọnyii n gbọ́, ni ède ilu ti wọ́n ti wá, bi awọn ọmọ-ẹyin ti n sọ ti iṣẹ nla Ọlọrun. O yà wọ́n lẹnu, ha si ṣe wọn; ṣugbọn Peteru, ẹni ti o kun fun agbara Ẹmi Mimọ́, bẹrẹ si i waasu fun wọn. O sọ fun wọn pe, eyi jẹ imuṣẹ asọtẹlẹ Joẹli. Bi o ti n waasu Jesu fun wọn, wọn ni igbọgbẹ ọkàn fun ẹ̀ṣẹ wọn, a si gba ẹgbẹẹdogun (3,000) eniyan là ni ọjọ naa. Wo iru iyatọ nla ti o wà ninu Peteru ẹni ti o sẹ́ Oluwa rẹ̀ ni ọ̀sẹ̀ diẹ sẹyin!

**A Ṣe Ileri Naa fun Wa**

Peteru sọ nipa awọn eniyan mimọ́ igba isisiyii pẹlu nigba ti o wi pe a ṣe ileri ẹbun Ẹmi Mimọ́ fun "gbogbo awọn ti o jina rére, ani gbogbo awọn ti Oluwa Ọlọrun wa ó pè" (Iṣe Awọn Apọsteli 2:39). O jẹ ohun pataki bakan naa fun awọn eniyan Ọlọrun ni akoko yii lati gba agbara Ẹmi Mimọ́ bi o ti jẹ́ fun awọn ọmọ-ẹyin nigba ni.

Gẹgẹ bi o ti ri pẹlu gbogbo ileri Ọlọrun, eniyan ni lati wà ni ipò ti Ọlọrun beere ki o to le ri agbara naa gbà. Awọn ọmọ-ẹyin ti ri igbala wọn si bá Jesu rìn fun akoko ti o lé ni ọdun mẹta. Lẹyin eyi O gbadura si Baba fun wọn: "Sọ wọn di mimọ́ ninu otitọ: otitọ li ọ̀rọ rẹ" (Johannu 17:17). Lẹyin eyi a sọ fun wọn pe ki wọn duro de ileri Baba, ifi Ẹmi Mimọ́ wọ ni.

Bakan naa ni ni akoko yii, eniyan ni lati mura tán lati gba ẹmi Mimọ́. Ki i ṣe pe ki eniyan ri igbala nikan o ni lati ri isọdimimọ́ pẹlu, iṣẹ oore-ọfẹ keji ti o daju. Nigba ti eniyan ba ri igbala, a wẹ ẹ̀ṣẹ rẹ̀ nù. Nipa Ẹjẹ Jesu ni a fi n sọ ọkàn di mimọ́. Nigba naa bi o ba wà a pẹlu gbogbo ọkàn rẹ, ẹni naa le ni ireti Ẹni Kẹta ninu Mẹtalọkan lati wá ki O si maa gbé inu ọkàn rẹ̀.

Eyi ni iriri iyanu ju lọ ti ẹnikẹni le ni. Ko si aapọn tabi ifararubọ ti a le ṣe ti o pọ̀ ju lati ni In, nitori ki i ṣe pe o n fun ni ni agbara lati ṣiṣẹ nikan ṣugbọn a tun maa mu eniyan wà ni imurasilẹ fun bibọ̀ Jesu, bi o ba n tẹ̀ siwaju lati maa rin ninu imọlẹ Ọrọ Ọlọrun. Ami kan naa ni o maa n farahan ni akoko yii ninu ẹni ti o ri I gbà gẹgẹ bi ti Ọjọ Pẹntekọsti – fifi ede titun sọrọ gẹgẹ bi Ẹmi ba ti fun ni ni ohùn – lai si ami yii ẹnikẹni ko le wi pe oun ri Ẹmi Mimọ́ gbà.

Nigba ti eniyan ba ri igbala yoo gba ninu Ẹmi Ọlọrun niwọnba nigba isọdimimọ yoo tun gba diẹ si i, nigba ti o ba gba Ẹmi Mimọ́ yoo kún ni akunwọsilẹ. Ibukun ti o pọ ju eyi ti o le gba ni a tú dà silẹ. A sọ fun ni pe, "Nigba isọdimimọ o ni ẹri Ẹmi, imisi Ẹmi Mimọ́ ninu rẹ, ṣugbọn nigba fifi Ẹmi Mimọ wọ ni, agbara naa sọkalẹ si inu rẹ lọhun ni iṣan Omi Iye.

**Ẹ̀kọ́ Wa**

Awọn ọmọ Ọlọrun nigba isisiyii kò ṣẹṣẹ ni i duro de ọjọ ajọ kan, tabi igba mẹta ni ọdun ki wọn to fi ara wọn hàn niwaju Rẹ̀. Wọn maa n ṣe ifararubọ wọn fun Un lojoojumọ. Wọn maa n fi fun Ọlọrun akọso wọn, ki i ṣe kiki idamẹwaa wọn -- idamẹwaa ti Ọlọrun -- ṣugbọn ọrẹ atinuwa wọn, gẹgẹ bi Ọlọrun ti bukun wọn. Ki i ṣe kiki owo ti wọn n gbà ni wọn n fi silẹ ṣugbọn wọn maa n fi akoko wọn, talẹnti wọn, ati ohun ini wọn silẹ, gẹgẹ bi ẹbọ fifi, ki o ba le sọ gbogbo ayé wọn di mimọ́. "Fi ohun-ini rẹ bọ̀wọ fun OLUWA, ati lati inu gbogbo akọbi ibisi-oko rẹ" (Owe 3:9).

**AWỌN IBEERE**

1. Igba meloo ninu ọdun kan ni wọn ni lati fi ara hàn niwaju Oluwa?
2. Sọ orukọ meji miiran ti a n pe ajọ Pẹntekọsti.
3. Ki ni ajọ yii n ṣe iranti rẹ̀?
4. Bawo ni Ọjọ Pẹntekọsti ṣe yatọ si awọn ajọ Pẹntekọsti iyoku?
5. Ki ni awọn ọmọ-ẹyin rí gbà lọjọ naa, eyi ti a ṣeleri fun awa paapaa?
6. Ta ni akọbi ninu awọn ti o sùn?
7. Bawo ni a ṣe le fi akọso wa silẹ?